# ARO KAN GBE ELESE MEJI LULE, EYI ARA!

**Ikede**

Aw ikede yi f u n gbogbo awon Okowo wa an asoju wa wipe, eni keni ti owo ba seku si owo re ki o tete fi ranse nitori gbogbo obun elo ti a fi ntewe irohin lo ti gbe owo leri.
Enikeni ti ko ba fi tire ranse ao da iwe re duro ao si an agbara lati gba owo wa ni owo re. Oletu

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

**Abo Idibo**

T. O. S. Benson gba 14,706
I. S. Adewale gba 12, 842
Ko padanu owo idogo re

VOL VII No. 428 LAGOS (SATURDAY) OJO ABAMETA AUG 13 1955, IYE 'OWO ELETI OFE KOBO MEJI. (2d)

## Aro Kan Gbe Elese Meji Lule

**Ibadan** Okunrin aro kan to nfi owo rin l'ora wo Kotu fun esun ija ati tete tita. (Gamble)

Nigbati okunrin aro yi ra wo inu apoti-eri, o ni on ko jebi esun ti tete sugbon on jebi ti ija. Adajo ni kio san ponun kan tabi ewon ojo merinla.

Giripa Okunrin kan ti on pelu aro na ja so wipe on ko jebi, nigbana ni Agb'ejoro Ijoba wa se alaye oro na fun adajo wipe ni ojo keje osu August 1955 yi, ni awon odaran mejeji yi bere si ja nitori owo ti nwon fi ta tete ti aro je ti okunrin giripa keji yi ki mole, ti ko fe ko fun aro.

Nigbati oro na dija, opelope Qlopa to se iranlowo lati le ja aro kuro lo'run giripa okunrin na. Awon mejeji fa arawon l'aso ya perepere. Awon mejeji l'o so wipe awon ko jebi esun keji, esun ti tete tita, (Gamble).

Adajo gba iduro fun won lori ponun medogun-medogun fun enikokan ati ki enia kokan duro fun won fun iye owo kanna.



ADEGOKE ADELABU

## Ejo Adelabu Ni Kotu Onireke

**IBADAN** Ofin ko mo Qba beni ofin ko mo ijoye, awon Qlopa tu perepere oro niwaju adajo ninu Kotu Onireke ni Ibadan nigbati nwon ro idi abajo ti Qgbeni Adelabu fi wa si Kotu.

Awon Qlopa ati Qgbeni Adelabu ti pari ejo riro won, idajo l'oku ti nwon nreti.

## AKIYESI

### LAGOS EXECUTIVE DEVELOPMENT BOARD

### ITIRE ROAD ESTATE

### AWON ILE IKO'LE SI FUN TITA

1. Ijoba ntun awon ile se ni Suru Lere, ti ao ma pe ni ILU QNA ITIRE, (ITIRE ROAD ESTATE) yio ni awon Opopo ona to dara, Oju agbara fun omi Ojo tabi omi aimo, omi mimu ati lilo to dara ati Ina onimonamona.
2. Awon ile na yio wa fun opolopo ile kiko ti ao ta patapata fun lilo kiko ile gbigbe si nikansoso.
3. Ijoba nkede nisisiyi pe ki enikeni to ba fe, kowe wa fun iwon bi ogorun ile ikole (100 Plots) Iye owo ti ao ta ni Sile mejila-abo (12/6d) fun iwon opa Onibu-merin (Square yard) owo 50X100 fun ile ikole kan yio je bi £350. ati 40X100 fun ile ikole kan yio je bi £275.
4. Gbogbo eni ti o ba fe ra okan ninu awon ile na nilati kowe, ki o toka si Ikede yi, iba a ti kowe ri, ki o tun iwe ko.
5. Gbogbo iwe ti enikokan bako nilati ni ponwun marun (£5) ninu, ao si da owo na pada fun eniti Ijoba ko ba ta ile fun u.
6. Gbogbo iwe ti enikeni ba ko ni lati lo bayi:-
   (a) Oruko enito kowe
   (b) Ibugbe Oluware, (Ako fe ibise tabi ti apoti ifiweranse)
7. Gbogbo iwe si nilati de ile ise L. E. D. B. ni Qgbon'jo osu September, 1955.
8. Enikeni ti a ba gba iwe tire ni lati ko ile ti o ya eto re (Plan) ki o fi ranse si ile ise yi, bi ijoba ba gba
9. Awon ile miran yio tun wa fun tita ni ona Itire (Itire Road) sugbon Ijoba le yi owo won pada, ki o ma bosi iye ti a ta awon ti isiwaju.

J. W. HENDERSON
Chief Executive Officer

## Jamba Salanga, Koto Igbonse.

**OKIGWI.** Isele buburu kan sele laipe jojo ni ilu yi, nigbati gonga igbo nse ti nwon ngbe ya bo enia merin mole ni isale koto to jin to ese mejidinlogun.

A gbo wipe awon enia mefa l'owa ninu koto nigbati koto na fi ya bo won mole, sugbon awon meji yo jade, ninu awon meji to yo, opelopo wakati ni awon enia fi nko erupe ki nwon to le yo okan jade, enikeji ni o ti sunmo oke.

Awon mejeji mbe ni ile iwosan (Hospital), ninu Okigwi. Ki Oluwa so wa lowo jamba.

## Iwe Irohin Gbogbo-Gbo

Iwe Irohin ELETI-Q F E ni Iwe Irohin t'omode-tagba ti o ye fun enikeni lati ma ka l'ososo, Iwe Irohin Eleti Qfe kun fun awon irohin aladun, irohin ere sise, irohin akojo to gbadun ati irohin awon oselu wa.

Akanse oro Olotu I w e Irohin Eleti-Qfe ko nse aroko ebu, ko nsoro abuku si enia o kun fun eko nipa ihuwa si ati isoro si enia, fun omode ati agba, tokunrin tobinrin E ma ka Iwe Irohin Eleti-Qfe ni gbogbo igba,

Eleti-Ofe ni Iwe Irohin to nkede ohun edun awon mekunnu, fun awon alagbara (Ijoba) ti nwon o fi bo ajaga kuro l'orun enia dudu ti ile Naijiria.

E MA KA IWE IROHIN ELETI—QFE
IWE YIN NI.

# ELETI QFE

A-NIU-WQN KO SE WI L'EJQ

EDITORIAL OFFICE & WORKS
28 Kesoko Street Lagos
P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAMS
"ETI-QFE LAGOS"
Phone 23370

VOL VII NO 428, LAGOS SATURDAY AUG 13 1955


## E Siwo Ninu Owo Abetele

Irohin ti a se si apakan iwe Irohin wa ose yi lati ilu Okuagbe, gegebi a ti gbo irohin na wipe omo meji ti o je omo ilewe Baptist fi owo abetele (Bribe) ranse si Qlola Alabojuto Eko ni Iwo-Orun nipa idanwo ti awon omo ilewe na se ti nwon ko gbo pa, ti nwon ko si gbo mu, ye ki o je ohun iyanu fun eniyan wa wipe owo abetele ti di nkan ti awon omo ilewe tun ni igbagbo si pe ko si wipe enia ni imo depo to le fi yege idanwo mo ayafi ki o na owo buburu yi si idi re.

Gege bi a ti gbo Irohin na, Qlola Alabojuto Eko iwe ti awon omo na fi owo abetele yi ranse si, ni o da owo na pada ti owo Ijoba fi te awon omo to fe gb'ona eru yege idanwo na.

Lona keji ewe, ti a si fi nilati sunraki ki awa woroko fi se ada pa ina owo abetele ki o ma ba gb'eran ni ile Naijiria wa yi, ti a nda'na lati di ominira, nitoripe, idena nla ni iwa owo abetele yio je fun wa gegebi Orile-ede.

Nitorina o to, o si ye ki irufe irohin yi je ohun edun-okan fun omoluwabi enia to ba ni fe ilosiwaju ilu re l'okan daju-daju, ko si ire kan ti owo abetele le se fun ilu wa lehin ibi. E je ki a fi eyi se ironu daradara, lomode, l'agba, ki a lo siwo ninu ideno buburu yi.

Eyi to ironu fun eniti o m'oye!

## Eja Ojiji Di Eja Aro

A gbo irohin wipe Oyinbo kan ti o sese de afe se iwadi iru eja ojiji, or si mejo ni a ni sile enia dudu. Nipa bayi, enikeni ti o ba mu eja Ojiji wa yio gba lowo re. A gbo wipe sile kan ati toro li o ra eja ojiji kokan-

Ni ibere osu July, okunrin Shekiri kan ti a npe ni Okoroboyo gba eja kan de, o si wipe, eja ojiji kan niyi, lati inu odo Bisi ni oe ti mu wa Sagbon, odidi ose meji ni on se ni eti odo ki on to ri eja Ojiji na mu.

Ni ose to koja lo ni on iba ti mu eja na wa, sugbon jiji ti eja na ji on lowo gba agbara kuro lowo on, nitori fun odidi ojo meta, ase ni gbogbo ara nro on. Nitorina, sile mewa li on yio ta fun oyinbo.

Nigbati Oyinbo wa yi o iru irohin bayi ko siye meji, o si gba pe eja Ojiji ni otito, lehin o si ra a ni sile mewa abo.

Lojo keji, okunrin a bi kan tun de pelu eja Ojiji alaiya pupa on lo tu asiri Okoroboyo wipe eyi ko na Ojiji bi kose eja Aro. Awon Qlopa si nwa Boyo nasiyi-


REDIFFUSION
THE BOX THAT TALKS SINGS & BRINGS MUSIC TO YOUR HOME
Costs less than 3d a day and gives you pleasure for 17 hours.
MAINTAINANCE FREE!
ARE YOU A SUBSCRIBER?


## Ojo Buruku Esu Gb'omi Mu.

ABIDJAN. Irohin ti a ri gbo lati ilu Abidjan Oke Okun ni wipe okunrin kan ara ilu na ti awon yoruba to wa l'ohun mba gbe ile po se jamba fun awon enia lojo ketala osu July, 1955.

A gbo wipe okunrin na pon ada re mu yanran-yanran, o si lo sa pamo sibi akitan ti awon anja ma nlo se igbonse lale, ki a ma fa ore gun, a gbo pe enia mejo ni okunrin na sa l'ogbe, obinrin yoruba kan pelu omo re lehin wa ninu awon to sa l'ogbe.

Awon enia merin l'oku ninu awon to sa l'ogbe, awon yoku wa ni ile iwosan. Bi oro na ba ti nlo si a o ma fun yin ni irohin re.

Ni ojo kedogun osu July 1955, kama ni ariwo tun ta ni ilu yi. Ij a tun gbo wipe okunrin kan tun lo sile ore re lati lo ki, nigbati o de ibe, o ba ibon kan ti nwon gbe ti si ara ogiri, ko mo wipe, nwon ti ki ibon na, o gbe dani, o nyewo, nibiti o ti na ibon na ba beni ibon dun gbau, o ba ore re to wa ki ni idi, gbogbo idi ore re ni ota ibun baje patapata, lesekese ni ore re na ku.

Enmo ki leyi o? ki Oluwa so wa lowo gbogbo ewu.




## Mob'olomo Yo

Ni ojo ose ti ise ojo ketadinlogun osu July, 1955 ni Qlorun fi omobinrin rubutu kan ta Qgbeni, L. A. Oyetunde (alias Qmo:Qla) ati iyawo re agunle-yinju A-lawu Adunni lore.

Lati ojo ti nwon ti bi omo na, ni baba omo ikoko-tape na ti bere si nawo bi sekere pelu awon egbon re titi di ojo ikomo jade.

Nigbati o di ojo ikomo jade ni agogo meje owuro ni, Lemomu ati awon isongbe re ti de si ile baba om , Lemomu Raji olohun'vo ni o ke wutuba, nwon si fun omo na ni oruko Sabitiyu Tinuoye. Qpolopo adura ni Lemomu se fun omo na ati awon obi re.

Lehin isomo-loruko yi ni faaji wa bere, ko si egbe gbajumo kan ti ko peju-pese sibe lati Sekondi ati T ko-radi, o bere lori egbe Qre mejo, egbe Qba-bi-Qlorun-kosi No, 1 ati No, 2 pelu akowe egbe Qgbeni J B, Akanbi ti ise ore baba omo pataki.

Akole sai daruko die ninu awon enia pataki pataki to wa sibi ikomo yi awon enibi JosephLaniyi, S; A, La-leye, Joseph Deji, Joseph Ade-niji, P.W. Onireti, S.L, Laleye Tiamiyu Obanikoro, John J. Oloyede, James Ajala, Bello Ajagbe ati Qlola S.A. Qjewale ti ise ore asiwaju baba omo.

Awon sanmori obinrin ti nwon je egbe ti ya omo na ko kere lojo yi, awon gbajumo to se itoju won alejo lojo na ni J n o Alamu, James Are n Solo-mon Sunday ati Amos Q run-yomi Afinju Tailor, ore baba omo. awon onje ati orisirisi oti, ajeti, ati Amuti, ni lojo yi.

Baba omo te gbogbo enia bi egbagbeje to wa sibi ikomo na loruu pelu jije ati mimu.

A ki awon asiwaju baba omo ku inawo, awon enibi Qlola Bello Ajagbe Shittu, Oyedeji Bello Oyegoke ati Salawu Qla-doye. Ogbomosho seyi na, ao tun se miran si asese tunse.

Ki Qlorun da omo na si.

## Ole Ko Abule Aregonga.

Irohin ti a gbo ni wipe awon ole lo ko gbogbo ile awon enia to wa l'abule Aregonga, abule na ko ju irin buso meji lo si Agege.

A gbo wipe awon ole na to adota enia ; nigbati nwon ro wo abule loru oganjo, nwon beresi ji awon enia to wa ninu ile won jade, nwon si to won jo, lehinna, nwon pin arawon si bi ona merin.

Gbogbo won l'o gbe ibon, Ada, ati ake ilewo dani, awon apa'kan da awon ara abule kuro larin abule won, awon yoku bere si ko eru ati gbogbo ohun ini awon enia na. Awon enia to fe se bi eni ntaku mo won lowo, alubole ni awon olosa na fi won se.

Ogbeni Yesufu Adeyinka ti ise Bale Abule Aregonga so wipe " Oro kowo nijo ti adete nje adigbon " ni ti awon ole na je, nitoripe tile-tona awon ni awon janduku enia ko lo rau - rau,

A gbo wipe oro na ti de owo awon olopa Ikeja nisi-siyi, ti nwon si nse iwadi re.

## QRQ OWO ORI OBINRIN

Qro na ti i oju suu gbogbo awon omo Ogbomosho si'le l'oko wipe owo ti a nfi npari obinrin kan ni Ogbomosho to kole bi ojule meren ti ao si re.

Niter'na, abe awon agbagba ki won o dakun, ki nwon o fiye denu, ki nwon o fiye de gbogbo ara na ki nwon o jeki a tele igba

Emi ni

Abel Adedokun.

P.O. Box 7

Ganbari Market

Ilorin.


## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.

A ma je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode.

OMORELA BABY MIXTURE

(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)

O wa lodo :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS






SIGA TO DARA FUN GBOGBO IGBA


## Oku Qlomo Gege La O Gbe

EJINRIN— Ni ojo kejo osu June 1955 ni alagba Qgbeni Badamosi ti ise Bale Ejinrin jade laiye, awon omo oloku se kisa nibi inawo isinku baba oninure na. Awon ebi Bale nawo nwon n'ara, oku na dun pupo.

Awon ara ilu Ejirin ni kilosubu te awon! awon na ko kere ninu inawo, adura ti wa ni ki Qlorun bo gbogbo nwon lasiri, ki o gbe baba rere na si afefe rere, amin.

ORI ADE KI IGBE OFO

Nipa oye Bale titun ti awon fe je ni Ejinrin e ti je asa won wipe eniti o ba je oye Balogun ni yio je Bale nigbati aye oye Bale b'a si sile, eniti o ba je oye otun Bale yio je oye Balogun.

Gegebi asa won, Qgbeni Shittu to je Balogun ni nwon mu fun oye Bale, nwon si mu Qgbeni S'oga Atakiri. otun Bale fun oye Balogun.

Ni ojo Kerinla osu August 1955, ni nwon yio se eto ifijoye fun won, ti nwon a fi Ewe Oye le won lori.

Ki Olodumare mu ojo ro,

## Ọro Esin, Ko Ye Mi To!

Olotu,

Jowo gba mi laye lati bere awon alaye oro yi lodo awon onimimo Igbagbo ati Imole.

A gbo wipe Anabi Monmodu ni o de gbehin awon Anobi on ni o si da esin Imale sile pelu.

Nje awon ti o ti wa siwaju re laila ri awon bi Buraimo ti awon Igbagbo npe ni Abrahamu Yesufu ti won npe ni Joseph.

Sulemona ti won npe ni Soloman, Ayuba ti won npe ni Jobu. Musa ti won pe ni Mose Issa ti nwon npe ni Jesu ati Moriamo ti won npe Maria.

Nje, ninu esin wo ni awon nwonyi nse ni aye ti won ti won fi ni oruko mejimeji bayi? Tabi won nse mejimeji po ni bi o.

E jowo e la awon oro na ye mi o.

Emi ni
S. O. Bello
Ara Abdjan-Adjewe


## Kere o!

A ti ni orisirisi ogun Germany to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ko to tan.
J. A. AJAO BROTHERS
Medicine Store
7, Egerton Road, Lagos

NOW,
AVAILABLE

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just write, Call, or
Phone 21371
IKORODU TRADING COMPANY
20/22, Balogun Street,
(P. O. Box 395) Lagos
AND
NEW COURT ROAD
IBADAN


## ISINMI DUN L'EHIN ISE

Ibadan Ọlọla Oloye Rotimi Williams ti ise alabotojuto Ijoba Iwo-Orun (Minister of Justice and Local Government) gba Isinmi lo si ilu Oyinbo, a si gbo wipe yio pada de ninu osu September, 1955 pelu Ogo Ọlorun.

Ajo yio dara, abo yio sunwon o.

## Ko S'enia Ko S'eranko.

**Jos.** Irohin ti a gbo lati ilu Jos ni wipe obinrin kan bi omo kan sinu ile iwosan, (Hospital) omo na je abami omo, ara re dabi ti enia, sugbon owo ati ese re pelu ori re ri gegebi ti Lagido - obo.

Nwon ni oju re ri korogba - korogba, o si ni ehin gangan-ran l'enu, gbogbo re wa ninu ori re to ri tofolo. Idaji eranko, idaji enia.

A gbo wipe nigbati oyun ti di bi osu mejo ni oko obinrin na ti so wipe awon onise - okunkun nmu eje iyawo on, eyiti ao tun ri lehin re ni eyi.

Iya to bi abami - omo yi si wa ninu Ile Iwosan.

Iru abami - omo wo l'eyi o?

## Omo Bale Na Iyawo Oba Nile Awori

A gbo irohin wipe, iyawo Oniba kan wa si eja Ọjọ lati wa ra nkan, a ko mo ohun ti o da ija sile, nse ni a ri odomokunrin kan ti a npe ni Gabriel ti o ko egba bo iyawo Oniba yi. Nigbati nwon si la awon meji, ti nwon bere ejo, awon meji si ro.

Sugbon nigbati eni ti o nda ejo na so fun omode kunrin na wipe, nje iwo ko mo wipe iyawo Oniba ni ise, Iru ede yi tunbo jeki omokunrin na bina o bere mu egba, o si tun ko bo obinrin oba yi.

Samo-samo omo oba Oniba ni o nda ejo fun won, o juwo si awon enia re, nwon ki okunrin na mole nwon lu u, nwon nmu lo silu Iba.

Okunrin na so fun won wipe omo Bale Apa ni on nse ori yio si je gbogbo awon ti o lu on ni iya. O si se, bi nwon ti nlo, okunrin na si wi pe on fe yagbe, enikan sin wo igbo. Nibiti onitohun gbe nwo o kakiri' okunrin na di eku n o si se opo enia lese

Nigbati irohin de odo Oni ba nwon bere si wa ekun na, nwon wa de ilu Apa, nwon ko ri, bayi ni o si fi di awa u.

## Ọdun Meji Larin Ọdun Kan

Lasiko kan, nigba aiye bale Akitay, nilu Ibadan a gbo wipe ijoye kan se afojudi si Bale ati awon ijoye Ibadan, nigbati nwon ranse pe ijoye alafojudi yi o ko, ko si lo da won lohun.

Awon ijoye ranse pe Ajele, Baba Ogundele wipe, ki o wa ba won ri si oro ijoye na. Nigbati oyinbo na de o gbo idi oro lenu totun tosi, o si wa da ejo wipe ijoye alafojudi na jebi, o si ni lati lo tunba fun Bale ati awon ijoye re.

Gbogbo awon ijoye ni o taku wipe; awon ko nigba ebe re ayafi bi oyinbo ba gbe ju s'ewon odun mejila. Oyinbo Ajele kigbe wipe Howu! iba oran ti ijoye yi da si ara re lorun ko to ohun ti a le gbe ju si ewon odun mejila. Nwon taku wipe ohun ti awon fe niyen. Ajele gba o si gbe ijoye na ju si ewon ni Agodi, sugbon ijoye na koiti lo ju odun kan lo ninu ogba ewon, nigbati awon ijoye tun ranse pe Ajele nigbati o de, awon ijoye so fun wipe, odun mejila ti pe, ki Oyinbo ba won yo ijoye na kuro ninu ewon.

Oyinbo na si dahun wipe, howu ni ojo wo ni nwon gbe ju si ewon? Ọdun kan sese pe ninu odun mejila ti e wipe ki a ju ijoye na si ni. Awon ijoye si kigbe baba! e o ha pa ni e? Ọdun mejila na ti pe. Oyinbo na tun bere wipe ki ni e ti se isiro odun ti nyin?.

Awon ijoye dahun pe odun Ifa, Odun Isu, Odun Egungun, Odun OrisaOko, Odun Bayanni, odun Orisa Ogiyan etc, etc. Bayi ni nwon siro gbogbo awon odun na o si pe mejila.

Sugbon oyibo na ko, ko fe da ijoye na sile. nitori ripe osu ti oyinbo ni nwon nsiro ni ogba ewon. Nwon dahun wipe, ese o, awa n a wipe ki o ko o sile, awa na li a si wipe ki o pa a re. Laifa oro na gun Ajele ni lati lo mu ijoye na pada wa sile.

Ibadan l'emo. e ko mo Lay po!

# Jamba Ina Sele Ni Ijebu - Ode

**Ijebu-Ode** Odomodebinrin kan ti ko ju omo odun mejila lo ni a gbo wipe ina to sele lokankan Afin Alayeluwa Oba Awujale jo omo na pa rau - rau loja Tuesday ti ise ojo keji osu August 1955.

Awon olopa nse iwadi ohun to fa jamba na lowo.


## WESTERN REGIONAL DEVELOPMENT BOARD

Lafia Canning Factory invite applications from suitably qualified Nigerians, over 25 years of age for the following posts:-

1. DEPUTY ENGINEER: duties will comprise supervision and maintenance of canning machinery, steam raising plant, electrical and ancillary equipment. Only applicants with sound training, both theoretical and practical, in mechanical engineering can be considered.

2. DEPUTY ACCOUNTANT: this post demands previous experience of accounting up to preparation of final accounts. A knowledge of cost accounting and stores systems would be an advantage.

3. ASSISTANT FACTORY MANAGER; who will assist with general administration, and should have previous experience in commercial organisation, in control of staff and knowledge of business methods. Since the factory operations are technological, previous engineering or scientific experience would be of value.

Applications giving full details of education, previous experience, age, and salary required should be sent to:-

LAFIA CANNING FACTORY,
PRIVATE MAIL BAG,
IBADAN.

not later than 20th of August, 1955.

## Irora Orikerike

Boya Kidi rin lo fa a.

Iṣẹ Kidinrin ni lati mu awọn idọti ti o mbẹ ninu ẹjẹ ara kuro nigbati ko ba ṣiṣẹ daradara idọti na awọ́ọ́ pọ sibikan eyi lo njẹki awọn orike bẹrẹ si dun ni.

Ohun ti a le fi werán ni wipe ka ṣe iranlọwọ fun Kidinrin na ki o le ṣiṣẹ rere, Egbogi De Witts na kakiri aiye ni asi ota egbogi na a Ọpọ iwe ni a ti ri gba lati ọdọ oriṣiriṣi enia ti nwọn nsọ iru iṣẹ ti De Witts ṣe fun nwọn. Danwo lọra ọkan ni ṣọbu egbogi.



Ohun to da wa loju ni wipe Egbogi DE WITT,S je eyiti a se tonitoni ohun elo re gbogbo lo si mo.

**DE WITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles


## Obinrin K n Bi Ọmọ Merin Po

ANKARA— Irohin ti a gbo ni wipe obinrin kan ti oruko re nje Abena Kwasimah, omo ogbon odun ti ise iyawo Kwame M nu, onise agbe ni Goaso l'agbegbe Ahafo bi omobinrin merin si ile Iwosan (Hospital).

A gbo wipe meta ku ninu awon omo na, ekeji, eketa gati ekerin sugbon eyiti o kobi mbe l'alafia pelu iya re.

Ise Oluwa awamaridi.

## Tani Le Ladi Ọro Yi Yemi? Idahun

OLOTU.

Jowo gba mi laye lati se alaye si ibere Ọgbeni Alufa Amuda Iwalewa to wa ninu iwe Irohin Eleti-Ọfe ti 30/7/55.

EKINI. Yio je si enu arare nitori wahala to se ki o to pa won.

EKEJI. O wipe on yio fi san gbese Baba re ni yio fun ni-iyen; nitoripe, baba re lo t ntoju re.

EKETA. Eyi to ti on yio ta lewin: Ọmo to bi ninu ara re ni yio fun ni iyen; nitoripe, nigbati o ba pe omo re yio san pada fun u.

EKERIN. Aparo kerin to ni on yio sonu; Iyawo re ni yio fun niyen; nitoripe eyi ko da obinrin doro wipe ki o ma se ko si e, ko si tun le ri gba mo lai. Ohun ti Aparo kerin fi je sisonu niyen.

Olotu, mo dupe o,
Emi ni,
Fasasi Yusuf
Box 7.
Ilorin.

## ADAJO JU ANYIAM S'EWON

Ọgbeni ti oruko re nje Dan Anyiam to lo ko ise lati ma ko awon enia ni bolu a'fesegba ni Adajo da ejo ewon osu medogun le lori.

Ohun to fa eyi ni pe nwon ni Ọgbeni Anyiam pelu awon miran ba Oyinbo kan se adehun lati te iwe owo eru nilu Oyinbo.

Anyiam ni idajo na ko te on l'orun o,


*Iwakọ mi pẹlu agbara*

**OVALTINE**




*Gẹgẹ bi ohun ti o ntun ẹjẹ ṣe ti osi nfun ara ni okun, gbidanwo lati ra akara Ovaltine jẹ, o fuyẹ, o tete nda ninu osi nṣe gbogbo awọn iṣẹ ilera ti Ovaltine papa nṣe.*

Gbogbo ọna jinjin ti mo ba nlọ ni mo nmu "Ovaltine" dani. Nitori ti o nfun mi ni ilera ati agbara.

**O ntun ẹjẹ ṣe, o mu ara lokun**

SPORTS TODAY

## PWD Vs RAILWAY

*The* first round of the Nigerian Challenge cup (formerly Governors cup) started in Lagos last Monday when S.C.O.A. after many hard struggles went over Dynamos 1-0. Marine outplayed Emandex 5 1, Casual succumbed to the Railway Boys at 1-8 By these victories SCOA, Marine and Railway have now qualified to play in the second round of the competition Railway will however meet PWD today for the second round.

The regional semifinals was played in the Eastern, Northern and Western Regions last Saturday. The result are Portharcourt 2 Calabar 2, Aba 3 Onitsha 2 Warri 4 Benin 1 Ibadan 5 Qyo 1, Kano 7 Kafanchn 1 Plateau 7 Minna 0

It is not certain which team will come to Lagos for the national Semi Finals and finals. The Eleti Qfe forecasts Warri for the West. Calabar from the East, Kano from the North and Railway for the Federal Capital.

Other Challenge Cup matches coming up are Garrison & SCOA on the 16 August, UAC Marine on the 20th August, Police & ECN on the 15 August, Police &ECN or Garrison SCOA on the 27 August.

**Polowo Qja Re Sinu Iwe Irohin**

**ELETI-QFE**

## Aradan Nervigora

Ogun ẹjẹ pataki fun imarale agba ati arẹmọ pipe fun awọn alaya papọ. O da a fun inarun, ẹjẹ dudo, isokun oju, gbigbọn ọwọ, ailesun, ailokun ainu, ati iru fẹ arun bawọnni. O jẹ ajidewe fun awọn ti a gbara wọn ndinko. On na gan ni ọkunrin yi lọ ti o fi di "Afẹsẹ kua bi ojo" 5/-6d pere ni pẹlu owo ọkọ 1/-6d. c. g. 7/-Post Free.




**The Egba Trading Aradan Stores**

144, Denton Street, 18, Denton Bridge Street P. O. Box, 2, Ebute Metta. Phone 44153

atun wa ni New Motor Park (Ogunpa Ibadan

**Chairs For Rent**

APPLY

OFE

NO. 3, AIBU STREET LAGOS

## AWO IKQRIN (RECORD) TI DECCA



yio mu awon orin ti o fe ati awon akorin wa sinu ile re

**Lo ra won ni sobu**

**S. C. O. A**

A ti da Eka titun kan sile ti yio tete ma fi awon ero ti o se pataki ranse.

**S. C. O. A.**

Head Office:- 40 Marina Lagos

Show Room Martins/Broad Street Lagos

ATI NI

Ibadan, Sapele, Warri, Onitsha, Calabar, Aba, Port Harcourt, Kano, Enugu, Zaria & Sokoto.

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23370